OWE
Pipe ni a npe gbon
A ki i pe go

# Irohin Yoruba

VOL IX NO 455 — MONDAY, MARCH 2[illegible], 1954 — KOBO KAN (1d)

E ma a polowo oja nyin sinu iwe **Irohin Yoruba**


# OBA OLOWO S'AJODUN KETALA

OWO--Ni ojo Abameta ti ise ojo ketala osu yi ni Alaiyeluwa Oba Olagbegi Keji Olowo Owo se ajodun odun ketala ti o gun ori oye. Ni ojo na gan an ni Oloye (Dokita) S. O Awolbyi, Obamuwagun Owo paapa se Iwuye tire gbogbo re wa dalu o di oyi damola. Awon enia pataki pataki ninu awon onise Ijoba, awon Alufa Ijo Onigbagbo ati awon enia pataki pataki miran ni ilu Owo ati lati awon ilu agbegbe Owo paapa lati Eko ni o pese si ibi Ajodun ati Iwuye na.

Gege bi asa Oba na, o se opolopo sara fun awon alaini o si ta, awon omo ile-iwe ti o ni iwa rere ati awon ti o se afinju julo nipa imototo ati awon ti o nse daradara ninu eko won lore. Ajodun ati Iwuye na dun o larinrin.

Ni ojo Aiku, Alaiyeluwa Oba Adegboye Kinni Orimolusi Ijebu Igbo ati awon enia pataki pataki ba Oba na lo se isin idupe ni ile-Ol run "St Andrew's Church." Eni-owo Bisopu S. O. Odutola ni o se isin idupe na, awon alufa Okusanya ati Olayemi ati Ayorinde ni o se amugbalegbe Bisopu na ninu eto isin na, Bisopu na so oro iwuri pupo lori ise rere ti Oba na se si ilu re eyiti o mu ki gbogbo ara ilu fi ni ite ododo si i.

Die ti aye wa fun lati daruko ninu awon alabasepo apapo Ajovo Ajodun Oba na ati Iwuye Obamuwagun ni Modile Eko (eniti o wa ropo Oba Eko), Olola Iyaafin Abakija, Iyaafin S. L. Akintola, Iyaafin S. O. Shonibare, Iyaafin H. O. Awolowo, Ogbeni J. O. Ogunleye Ogbeni Crossdale (Aje e Port Harcourt,) Oloye Adajo Kekere Akin Adeshigbin Lisa, Ojoo, Oloye Adekunle Coker, Odolin Iporo, Oloye Esther Adeshigbin, Lika Ojoo, Oloye Bank Anthony, Iyamokun Ojoo, awon Iyaafin Bosun Morinho, Alice Evelyn Brown, Joko Pratt, G.E. Roberts, Jose Macaulay, Iga, Joseph, Messrs Pekun Dawodu, J.F. Fakoiujo, S.B Roberts, I.O.S. Osisanya, B. Awoliyi, Olola S.B Aruwajoye, Dokita Shasegbon, Ogbeni Dan Cole ati Iyaafin re. Awon Iyaafin Ayo Akiwowo, B.A. Akerele, Remi Delano, Ebun Wilson, Clement Taiwo, Lolo Labinjo, Phebean Coker, awon Omidan Teni Wilson ati Modupe Johnson, awon Oloye Ojomu, Oshere, Aiana, Sashere, Ariyo ati Owadogbon.

Ki ade pe lori ki bata pe lese. Kabiyesi!



Lehin isin Idupe ni nwon ba Olowo ya aworan yi Bisopu Odutola ni o kanyin si Olowo, Oba Orimolusi Ijebu Igbo, A. Olukoya Oga Ile-ise U. A. C. ati Ogbeni Crossdale, Ajele Port Harcourt.

## Ayodele Lijadu Ku



Ni ojo Eti ti ise ojo kekandinlogun osu yi ni Ogbeni Ayodele Oluwole Lijadu jalaisi ni igbati o di eni odun metaleladota ninu irin ajo re laiye.

Ogbeni Ayodele Lijadu ti o di oluogbe yi je okan ninu awon asiwaju oniwe-irohin, nitoripe fun opolopo odun ni o fi se Olotu Iwe Irohin "Daily Times".

Nigba ti ogun-ajaiye Keji bere, o lo si ilu Burma, o si nse ise iwe itopataki fun t'ogun "Official War Correspondent."

Nigbati o pada de lati ogun ni o bere ise ni Ile Ise Irohin Ijoba [Public Relations Department] ninu odun 1946.

Nigbati o si di 1948 ni o gb'aye ipo giga, o di "Press Officer" ni Ile ise na. O je okan ninu awon ti Oba ilu oyinbo fi oye M. B. E. da lola ninu odun 1952 nigbati Oba na n'se ojobi fun iwa rere ati akikanju Ologbe na ninu ise.

(Wo oju ewe kerin)

## Daily Service fi £900 Tanran.

Ni ojo Aje ti ise ojo kejilelogun osu yi ni Adajo, Agba Ogbeni Henri de Commarmond ti Kotu nla da awon Olotu Iwe Irohin Daily Service lebi lori esun oro afojudi si Ijoba. O si ni ki nwon fi edegberun ponun (£900) tanran na.

Pataki oro n esun ti Ijoba fi mba awon Olotu Iwe Irohin Daily Service se ejo si ni pe nwon te oro kan jade ni ogunjo osu kokanla odun ti o koja yi lori ipinnu Ogbeni Oliver Lyttelton alamojuto awon ilu amona Ijoba Geesi nipa ki Eko wa Gedegbe eyiti awon alase

(Wo oju ewe keri )

## A DA EGBE ACTION GROUP ODO SILE NI EBUTE METTA

EKO--Ni ojo Abameta ti ise ogunjo osu yi ni nwon da Egbe Action Group Odo "Action Group Youths' Association" sile ni Ebute Metta. Nwon si se ipade na ni Gbongan Apejo Lisabi, Ebute-Metta. Opolopo awon enia pataki pataki l'omode ati l'agba ni o pe si ibe lojo na.

Dokita Akanni Doherty, Alaga eka Egbe Action Group Eko fi han ninu oro iwuri re pe Egbe Odo, Nigerian Youths Movement ni o se okunfa ise ribiribi ti awon ara ilu yi nse fun idagbasoke ilu Nigeria.

Dokita Doherty so pe ninu awon ise iwuri ti Egbe Nigerian Youth Movement na se ni sise Ijoba tabi Eto ilu ti o bo si owo awon ara wa [illegible]

Ogbeni R. A. Fani-Kayode Olori Egbe Action Group Youths Association si won leti iru ise ribiribi ti o wa fun egbe na lati se bi ija eto fun idaminira awon eyiti awon nja lowo lowo yi pe ki nwon mase se are nipa re.

Olola F. O. Awosika gba won ni imoran pe ki nwon wa ni ifowosowopo ki nwon si ma a tele ofin Egbe na. Ogbeni

Wo oju ewe kerin


## SPECIAL ANNOUNCEMENT

## LAGOS REDIFFUSION

Over 22,000 people have applied for Rediffusion in Lagos. This demand has caused the system, which was designed for a maximum of 20,000, to show signs of overloading.

To ensure good service to all existing and intending subscribers it is essential to increase or reconstruct the wiring in certain areas.

It is therefore announced with regret that no further connections **or reconnections** can be made in the Lagos Area until this has been done. The work will be completed as quickly as possible.

**R. T. HARRIS**
*MANAGING DIRECTOR,*
*REDIFFUSION (NIGERIA) LTD*

# IWE SI OLOTU IROHIN YORUBA

## Idahun Si Ibere Oyinloye

ALAFIA ni fun nyin ati fun gbogbo awọn ọgagun Ilbala. Adura mi ni pe ki Ọlọrun fun gbogbo wa na ni Iṣẹgun ni ikẹhin ọjọ o. Amin.

Eyi ni Idahun alọ Peter A. Oyinloye [Irorẹ] Omu Aran, Ilọrin, ti o jade ninu Irohin Yoruba ti ọjọ 28. 12. 53. Orukọ awọn ẹranko na ati ti awọn agutan na ni wọnyi:-

1 Ikoriko na ni Nebkadnesari Ọba. 2. Ẹkun ni Ina Ileru. 3. Kiniun ni Iho Kiniun. 4. Awọn agutan mẹrin na ni [1] Daniel (2) Ṣadraki (3) Meṣaki ati 4. Abednego. [5] Idi rẹ ti awọn ẹni wọnyi ko fi le pa wọn lara nipe nwọn gbẹkẹle Ọlọrun wọn tọkan tọkan. On na si ndabobo wọn.

Ki Ọlọrun fun gbogbo wa ni ore ọfẹ kikun ki awa na le gbẹkẹle Ọlọrun patapata fun abo lọwọ awọn ọta ni akoko ti wa yi o. Nikẹhin ki a si le ni iye ti koni pẹkun. Amin.

Emi ni,
Mof'ọlọrunṣọ Ọlanipẹkun,
Ibadan.

AKIYESI - A dupẹ lọwọ Mofọlọrunṣọ Ọlanipẹkun Ibadan fun itara rẹ lati dahun alọ Bibeli ti arakunrin Peter A. Oyinloye pa na. Ṣugbọn eyi ti a kọ si isalẹ yi ni idahun alọ na ti Oyinloye funra ara rẹ fi ṣọwọ si wa:-

Agutan kini ni Adamu O tilẹ ngbọ ede awọn Ẹranko. Ko si si ti pe nwọn nri i sa rara nigba na, ki on to dẹṣẹ si Ẹleda rẹ. O si ma nrin larin wọn depo pe on lo f'orukọ fun wọn lo'ọtọ. Ifẹ ti Oluwa ni si i lo fa eyi. Gen. 2: 19. 20.

Ẹnikeji ni Noa on pẹlu gbọ ede wọn de ayekan nwọn si gbọ tirẹ na daju. Nitoripe Ọluwa ko ka ẹṣẹ si Noa lọrun, ọna rẹ si wu Oluwa. Gen. 7: 2.3.8.9. 14-17.

Ẹnikẹta ni Nebukadnessari Ọba Babeli sugbọn fun ijiya ẹṣẹ ni. Dan. 4: 22.29.

Ẹnikẹrin ni Kristi Oluwa wa. Mk. 1: 13. nitoripe Olododo ni on, awọn Ọmọ Ọlọrun nikan lorilẹ aiye nigbaatun kọ Aiye yio si tun wa ni Ọrẹ pẹlu awọn ẹranko gẹgẹ bi ti ọgba Edeni.

Isa. 11: 6-9 Isa. 65: 17, 21-25. Rev. 21: 1. 2.

OLOTU



Awọn ti o njo pẹlu Ọba Ọlọwọ ·i ni Iyaafin Awolọwọ ni ọwọ ọtun ati Iyaafin S. O. Shonibarẹ ni ọwọ osi.



Ayaba Yeyese (ni o joko lọwọ ọtun) Ayaba Yeyesorun ni o joko lọwọ osi, awọn Iyawo Ọba Ọlọwọ meji ti o nde ade, awọn ni o joko ti nwọn npin ẹbun fun awọn ọmọ ile iwe ti o ṣe daradara.

## Eti to ba gb'alo ni gb'abo

OLOTU, Inu mi yio dun pupọ bi ẹ ba le gba mi laye lati sọ goolohun ọrọ kan tabi meji lori edeaiyede ti o ti wa ninu ilu Ṣẹpẹteri.

Ẹnyin ara ilu Ṣẹpẹteri ti ẹ nfẹ idagbasoke ilu na yio ṣe iranti pe ni nkan bi ọdun kẹta s'ẹhin (1951) ni Ijọba ti fi wa lọkan balẹ pe ile-ifiweranṣẹ [Post Office] yio wa ninu ilu yi, ṣugbọn ninu ọdun keji s'ẹhin [1952] ni Ijọba ṣe iyọnda lati kọ ile na, edeaiyede wa bẹrẹ lori nihin-ni-a-o-mọ-si, a-ko-ni-mọ ọ-si-ibẹ," ijiyan yi mu ki ilu da si meji.

Awọn enia pataki pataki si wa lati awọn ilu Igboho, Ọyọ, Iseyin ati awọn ilu miran ti nwọn wa ṣe atunṣe ọrọ na, a dupẹ pupọ lọwọ awọn alatunṣe ọrọ na. Ki Oluwa tun ile ati ọna awọn onilaja na ṣe.

Ọpẹ ni fun Ọlọrun ti O tete fa ni fi opin si edeaiyede na. Gbogbo ẹnyin ọmọ ilu Ṣẹpẹteri ti ẹ wa ni idalẹ, ẹ fi ọpẹ fun Oluwa, ki ẹ si je ki ayọ nyin le ọkan si ki ẹ jẹ ki a wa ni iṣọwọpọ lati ṣiṣẹ rere fun igbega ilu wa.

Ki Ọlọrun O ṣe Amọna wa o.

Olotu, ẹ ṣe pupọ, ẹ ko ni si ṣe o.

Emi ni,
E. B. A. Agbọmọbini
Bolgatanga
P. O. Box 2. 7- N. T. S

## Omo Imapo Se Ipade

OYAN-- Ni ọjọ Ẹti ti iṣe ọjọ kẹjọ oṣu kinni ọdun yi ni awọn ọmọ Imọpo ni Ilu Ọyan ṣe ipade alarinrin kan ninu Ile Gbẹiyẹ Ọyan. Bi ilẹ ọjọ na ti mọ ni ero ti nde lati awọn ilu agbegbe Ọyan bi Igosun ati Ijabe Iba, si inu ile ti nwọn yio ṣe ipade na, lẹhinti nwọn jọ ki wọn ti nwọn yọ ki wọn tan ni nwọn wa fi orisirisi onjẹ aladun ati ọti ati siga ati obi ṣe wọn lalejo.

Ki o to to dede agogo meji ọsan ti nwọn yio bẹrẹ ipade na gbogbo ile Gbẹiyẹ Ọyan ti kun pupọ fun awọn enia pataki ti o wa fun ipade na, awọn ti o pe sibẹ, je adọjọ enia. Ninu

(Wo oju ewe kerin)

## Lawuyi Fo Wa S'Eko

EKO--Ni ọjọ Ọjọbọ ti iṣe ọjọ kejidinlogun oṣu yi ni Ọgbẹni S. B. Lawuyi ti iṣe Aṣoju Olotu Iwe Irohin Yoruba ni Nkawkaw, Gold Coast ba ọkọ ofurufu fo wa si ilẹ yi lati wa ra ọja diẹ gẹgẹ bi ọna owo rẹ.

Ni ọjọ keji ti o de ni o lọ si Abẹokuta fun ibẹwo ọmọ rẹ ni Ile Ẹkọ Giga awọn Ijọ Onitẹbọmi idi-Aba Abẹokuta, o si tun ṣe ibẹwo awọn ara ati awọn ọrẹ rẹ ki o to pada si Eko.

Ni ọjọ Aje ni o wa si ọdọ Olotu. Ninu alaye ti o nṣe fun Olotu ni a ri i gbọ pe ọpọ ninu awọn arakunrin gbogbo ti o wa lọhun ni o fẹran, a ntọrọ iwe irohin ka nipa bẹ ẹ enia mẹwa le dirọ mọ iwe kan.

Haba! kini i ba fa a, "Elo l'a ng m'okun Wundia t' adelebọ ntarin wọ'di" ọrọ ni ki onikaluku ni tire ni ipamọ lati ma fi ṣe akajuwe ọrọ nigbakugba, ẹ tete sare lọ ra tiayin lọdọ Ọgbẹni S. B. Lawuyi, P. O. Box 27, Nkawkaw, Gold Coast, "gba mu ko tan iba," kobọ kan pere ni, ki Ọlọ-

(Wo oju ewe kerin)

E MAA KA
IWE IROHIN YORUBA



## OMO IMAPO SE IPADE

Lati oju ewe kẹta

Ipade na nwọn sọ bi Awọn Omọ Imọpo yio ti ṣe ma a dagba soke ati bi awọn yio ti ṣe ma a ni ilọsiwaju ninu Ẹgbẹ wọn ti nwọn da silẹ na.

Nwọn si ṣe ipinnu lati ma a da owo ati lati yan akapọ. Lẹhinna ni nwọn ya foto pọ fun iranti ọjọ na, ki nwọn si to dagbere fun awọn Omọ Imọpo ti nwọn wa lati agbegbe ilu Ọyan.

A ki awọn oninawo ẹjọ na, awọn Ọgbẹni Joshua Seriki ati Moses Adeyẹmọ, Oyinkan Iya Ọlọja, Ibidunni ati Ọgbẹni J. A. Yọde Akọwe Ẹgbẹ na ti iṣe Aṣoju Iwe Irohin Yoruba na'wo na'ra lọjọ na, irohin ko to amojuba ni inawo ti nwọn ṣe. Aṣeyiṣamọdun o.

## Lawuyi Fo Wa S'Eko

Lati oju ewe kẹta

run Ọba maṣe nyọn ni kosi-kosi o. Amin.

Lẹhin ti nwọn fi ọrọ jomitoro ọrọ tan ni Olotu ba mu u yika ile iṣẹ wọn, o si fi gbogbo irinṣẹ itẹwe titun gbogbo ti nwọn ni han an ati bi nwọn ti ṣe nlo wọn. Inu rẹ si dun si gbogbo alaye ti awọn ti nṣiṣẹ nibẹ ṣe fun un.

Ni ọjọ Iṣẹgun ti iṣe ọjọ kẹtalelogun oṣu yi na ni o ba ẹkọ ofurufu fo pada si ibujoko iṣẹ owo rẹ ni Oke-Okun. (Nkawkaw, Gold Coast). Alọ a dara, abọ asunwọn o-Odidẹrẹ ki i ku s'oko iwajẹ o.

## Odutola di Ogbeni Oja Ijebu-Ode

IJẸBU-ODE Ni ọjọ Abamẹta ti iṣe ogunjọ oṣu yi ni Ọlọla T.A. Odutọla di Ọgẹbni Oja Ijẹbu-Ode. Ninu ọdun 1948 ni Ọba Alaiyeluwa Daniel Adesanya Gbelegbuwa Keji, Awujalẹ Ijẹbu-Ode ti fi i jẹ oye na ki o to ṣẹṣẹ bẹrẹ si ṣe iwuye na ni ọjọ Abamẹta ti a juwe s'oke yi.

Ọgbẹni Odutọla jẹ ọkan pataki ninu Ẹgbẹ Action Group, o si jẹ Aṣoju ilu Ijẹbu ninu Igbimọ Asofin Iwọ-Orun Nigeria ati ninu Apapọ Igbimọ-Nla Asofin Nigeria.

Ogunlọgọ awọn enia pataki pataki ati awọn Ijoye Ijẹbu-Ode ni o ntọwọ wa ki i ti Oloye Ọgbẹni Oja na si nṣe wọn ni orisirisi alejo. A ko tun ṣẹṣẹ le sọ ti ogunlọgọ ọpọ enia ti o wa ki i lati igun mẹrẹrin ilu abẹ Ijọba Iwọ-Orun.

Oye Ọgbẹni Oja yi jẹ oye aṣiwaju fun gbogbo awọn Ijoye, eyiti o duro fun oye Basọrun [Prime Minister] ni ilẹ Yoruba. Ki iṣe oye idile, Ọba fi nda ẹniti o ba yẹ fun un lọla ni, ẹniti o si jẹ oye na kẹhin ni Ijẹbu Ode ni Oloye Olotufore ti o ku ninu ọdun 1906.

Ninu awọn Oloye ti o wa ba ṣe ẹyẹ na nia wọn Gafaru Oniyamẹta, Olisa Ijẹbu-Ode, Olotufore Ijẹbu-Ode, Buraimọ Ọlapoẹkun, Y.O. Ọnabule, Ogunade, Apebi Odogbolu, Obaniowo Agọ-Iwoye ati Mọlade Odogbolu. Oye amọri o.

# Aworan yi ni ti iwuye Olola T. A. Odutola



Oloye T. A. Odutọla Ọgbẹni Oja Ijẹbu-Ode, on ni o ṣikeji lọwọ otun, Oloye Olisa ni o wa ni ikangun lọwọ osi, Oloye Ogunade, Apebi Odogbolu ni o wa ikangun ọwọ ọsi Oloye Odutọla, Oloye Ẹgbọ Ijẹbu-Ode ni o kangun ṣọwọ otun.

## Ayodele Lijadu Ku

(Lati oju ewe kini)

O jẹ ẹnikan pataki ni igba aiye rẹ ninu Ẹgbẹ "Island Club" Ẹgbẹ Yoruba Tennis Club" ati ọkan ninu Ẹgbẹ Reformed Ogboni Fraternity.

Ni ọjọ Aje ti iṣe ọjọ kejidelogun oṣu yi ni nwọn ṣe isinku rẹ, nwọn ṣe isin ikẹhin fun oku rẹ ni Ile Isin Ọlọrun ti Cathedral Church of Christ, Lagos. Lati ibẹ ni ogunlọgọ enia si ti tele oku rẹ lọ sin si Itẹ Ikoyi. Ki Ọlọrun f'Ọrun kẹ ẹ o.

EMA A KA IWE
Irohin Yoruba

## Daily Service Fi £900 Tanran

Lati oju ewe kini

Ijọba na ṣe akiyesi pe ọrọ na mu afojudi dani o si le mu awọn enia ma a fi oju tinrin Ijọba Gẹẹsi.

Adajọ na ni ti ko ba si ti Agbẹjọro Oniwe-Irohin na ti o tete gba pe nwọn jẹbi ni, ati pe ti ko ba si pe o jẹ iwe aiumọ-sọwọpọ kọ ni, ki ba ti si ohun ti o le da on lọwọ kọ lati ma ṣe idajọ ẹwọn fun ẹṣẹ na.

Agbẹjoro Iwe-Irohin Daily Service Lọya L.J. Dosunmu na si bẹ Adajọ na pe ki o jẹki awọn san owo na ni adasan l'ẹmẹrin Adajọ na si gba bẹ ẹ.

## Egbe Action Group

Lati oju ewe kini

H. A. B. Fasinro gba wọn ni imọran pe ki nwọn ripe eto ati iṣẹ rere Action Group na ni o wu awọn lori de aye ti nwọn fi wọ Ẹgbẹ na ati pe ki i ṣe nitori ti ẹnikan.

Ọgbẹni J. O. Oduyẹlu si da a ni imọran pe ki nwọn da Ẹgbẹ Action Group Ebute-Metta silẹ, gbogbo awọn ogunlọgọ enia pataki pataki ti o pe sibẹ si ti ara mọ ọ ki nwọn to tuka. Lati igbana lọ ni Ẹka Ẹgbẹ Action Group Youth's Association ti fi idi mulẹ ni Ebute-Metta.

No. 39

# PUBLIC NOTICE

## Government Valuation Unit

The Government Valuation Unit, now occupying premises at 27/29 Reclamation Road, Lagos will move into new office accommodation at Moloney Street, Lagos (formerly occupied by Prisons Department) as from the 7th of April. The telephone number remains unchanged as 23397.

The unit will be closed to the Public on April 5th and 6th.

The Lagos Town Council Assessment Officer will continue to share offices with the Government Valuation Officer.

ABIYAMO ETI RE MELO?

'YARO' Awogba Omode!



Abiku ọmọ nda ọ l'amu? Awọn arun wonyi ha nyọ ọmọ rẹ enu bi?

AIPERI, ORERE, INU-IWO, OSI, IGBONA, IKO, IGBẸ-ORIN, OTUTU, IBA, JEDIJEDI ati orisirisi awọn arun miran ti ima yọ ọmọde l'enu ni igba EHIN HIHU. Lọ ra "YARO" awogba arun ọmọde fun gbogbo awọn arun ti ima yọ ọmọde ienu.

"YARO" ko ni meji ni gbogbo ilẹ Nigeria.

Ki iwọ ki o ri i pe oruko "YARO" ni o wa lara igo na ki nwọn ma ba ta ADAMODI egbogi miran fun ọ.

SOLD BY:-

IYIN OLUWA MEDICINE STORES
(K. B. Savage, Chemist and Druggist)
88, Broad Street, Lagos
AND ALL DRUG STORES throughout Nigeria.

REDIFFUSION
FOR LESS THAN THREEPENCE PER DAY
you can obtain
NEWS
MUSIC
EDUCATION
ENTERTAINMENT
FROM 6 A.M. TO 11 P.M.
IN YOUR OWN HOME
APPLY AT OFFICES IN LAGOS, IBADAN & ILESHA.

Printed & Published by the Service Press Ltd
5/7 Apongbon Street, Lagos.